# IKILỌ NIPA AWỌN IKOOKÒ

## Iṣe Awọn Apọsteli 20:1-38

## ẸKỌ 347 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Bi ẹnikan ba wasu ihinrere miran fun nyin jù eyiti ẹnyin ti gbà lọ, jẹ ki o di ẹni ifibu" (Galatia 1:9).**

### Pipa Igbagbọ́ Mọ́

Paulu fẹrẹ pari irin-ajo rẹ̀ kẹta fun itankalẹ Ihinrere. Ọpọlọpọ eniyan ni o ti ri igbala nipasẹ iwaasu rẹ̀; ṣugbọn nibi gbogbo ti o lọ ni a ti ri awọn eniyan ti wọn tako Ihinrere ti o n waasu.

Iṣẹ iranṣẹ Paulu ki i ṣe eyi ti o rọrun rara. Oluwa ti sọ fun Paulu tẹlẹ nigba ti O kọ́ pè e pe yoo jiya pupọ nigbooṣe. Ṣugbọn Paulu kò jẹ ki eyi ṣi oun lọwọ iwaasu rara. Lai fi gbogbo inunibini ti o ti fara dà pè, sibẹ o sọ ni opin ẹmi rẹ̀ pe, "Emi ti pa igbagbọ́ mọ́."

Ọpọlọpọ awọn ọ̀dọ́ ti i ṣe iranṣẹ Ọlọrun ni o ti bẹ̀rẹ pẹlu igbona-ọkàn ati itara lati waasu gbogbo Ọrọ Ọlọrun; ṣugbọn ni ọjọ ogbó wọn, wọn ti gbé itara ati waasu gbogbo Ọrọ Ọlọrun sọnu. Bawo ni ọpẹ wa ti pọ̀ tó fun apẹẹrẹ eniyan bi ti Paulu, ti o fi hàn gbangba wi pe o ṣe e ṣe lati kún fún itara ati lati wà ni iduro ṣinṣin titi opin ẹmi wa. A si tun dupẹ fun awọn apẹẹrẹ ti a ni ni akoko ti wa yii pẹlu -- awọn wọnni ti wọn ti jẹ olooотọ titi de oju ikú.

Paulu ti ṣe iṣẹ ti Oluwa pe e lati ṣe, lai fẹ mọ bi awọn eniyan gbọ́ ti rẹ̀ tabi bẹẹ kọ́. O wi pe: "Emi kò fà sẹhin lati sọ gbogbo ipinnu Ọlọrun fun nyin."

### Ọsẹ Kan ni Troasi

Paulu ati awọn ọrẹ rẹ̀ duro fun ọjọ meje ni Troasi, ni Ọjọ Oluwa wọn lọ pade awọn ọmọ-ẹyin ti o wà ni ilu yii lati jọsin. Ṣaaju akoko yii awọn ọmọ-ẹyin wọnyii kò ni anfaani pupọ lati gbọ́ ọ̀rọ lẹnu Paulu, nitori naa o ni ohun pupọ lati ba wọn sọ. O fa iwaasu rẹ̀ gun di ọganjọ-oru. Ọmọkunrin kan wà nibẹ ti o n tò ògbé. O joko ni oju fèrese, nigba ti oorun wọ̀ ọ lara o si ṣubu lulẹ. Ori okè kẹta ni o ti ṣubu lulẹ, o si kú. Gbogbo awujọ ni o daamu pupọ. Ṣugbọn Paulu ni igbagbọ́ pe Ọlọrun yoo dá ẹmi ọdọmọkunrin naa pada. O ṣe gẹgẹ bi Elijah ati Eliṣa ti ṣe nigba ti wọn ji ẹni ti o kú dide: o "wolẹ bò o," o gbá a mọra, o si fi gbogbo ọkàn rẹ̀ gbadura. O sọ fun awọn eniyan naa ni ohùn jẹjẹ pe, "Ẹ má yọ ara nyin lẹnu; nitori ẹmi rẹ̀ mbẹ ninu rẹ̀." A ti gbe e dide ni orukọ Jesu Kristi, nitori ẹni ti Paulu ti mura tán lati jiya ati lati kú.

Ninu gbogbo iṣẹ-iranṣẹ Paulu ohun ti o jẹ́ kókó iwaasu rẹ̀ ni Jesu Kristi, Ọmọ Mimọ́ Ọlọrun. Nitori pe o fi gbogbo ọkàn rẹ̀ gbẹkẹle Jesu, eyi jẹ́ ki o le ṣe ọ̀pọ iṣẹ-iyanu ni orukọ Rẹ̀.

### Kò si Ọrọ Didun

Paulu ti gbé ọjọ pupọ ni Efesu bẹẹ ni o tun n fẹ lati bá awọn alakoso ninu ijọ ti o wà nibẹ sọrọ. O mọ̀ pe oun kò tun ni wá si ọdọ wọn mọ́, nitori naa o pè wọn lati sọ ọrọ itọni ikẹyin fun wọn, ati lati kilọ fun wọn nipa ewu ti o wà niwaju.

Paulu ti waasu pe a ni lati tún eniyan bi. O ti kilọ fun awọn eniyan nipa ẹ̀ṣẹ, ibọriṣa, ati awọn ti wọn fẹ lati lọ si Ọrun nipa ṣiṣe iṣẹ rere dipo ki wọn gbà Jesu gbọ́. Oun kò sọ "ọ̀rọ didun" fun awọn eniyan naa ri lati fi wá ojurere wọn, ati lati jẹ́ gbajumọ laaarin wọn. Ọrọ igbala ẹmi wọn jẹ ẹ lọkan. O mọ̀ wi pe ọjọ kan n bọ ti gbogbo awọn ti wọn n gbọ́ iwaasu rẹ̀ yoo duro niwaju Jesu fun idajọ. Bi wọn kò ba bọ lọwọ ẹ̀ṣẹ a o dà wọn sinu iyà ainipẹkun.

Ki ni yoo ha ti ri bi Paulu kò ba sọ fun wọn pe a ni lati gbà wọ́n là kuro ninu ẹ̀ṣẹ? Wọn yoo ṣegbe, oun yoo si jẹbi! Ṣugbọn Paulu le wi nisisiyii pe, "Emi kò fà sẹhin lati sọ ohunkohun ti o ṣanfani fun nyin." O tun wi pẹlu pe "Ọrùn mi mọ́ kuro ninu ẹ̀jẹ enia gbogbo."

### Awọn Oluṣọ

Bawo ni inu rẹ̀ ti dùn tó lati ri pe oun ti sa gbogbo ipa oun lati fi ọna igbala hàn wọn! Wọn ki yoo le tako o ni ọjọ idajọ wi pe, "Iwọ kò sọ fun mi."

Wolii kan kọ akọsilẹ nigba kan wi pe bi olusọ kan ba kuna lati kilọ fun awọn eniyan nipa ibi ti n bọ, bi ibi ba si bá awọn eniyan naa, Ọlọrun yoo beere ẹ̀jẹ wọn lọwọ olusọ naa. Paulu kilọ fun awọn ara Efesu pe ikú li ere ẹ̀ṣẹ, ati pe wọn ni lati ronupiwadà ki a si gbà wọ́n là ki wọn to le lọ si Ọrun; nitori eyi ọrùn rẹ̀ mọ́ kuro ninu ẹ̀jẹ wọn.

**Awọn Ikooko Buburu**

Awọn eniyan ti o wà ni ijọ Efesu gba iwaasu Paulu gbọ́ a si ti gbà wọn là, ṣugbọn eyi ki i ṣe opin ija ti wọn ni lati bá Satani jà. Paulu sọ fun wọn pe lẹyin ti oun ba ti lọ tán awọn "ikõkò buburu" yoo wọ̀ aarin wọn, "li aidá agbo si."

Ki i ṣe awọn ẹranko ni o n tọka si nihin yii bi ko ṣe awọn oniwaasu èké ti yoo wá saarin wọn lati wá bì gbogbo iwaasu Paulu wó. Paulu wi pe, "Ṣugbọn bi o ṣe awa ni, tabi angẹli kan lati ọrun wá, ni o ba wasu ihinrere miran fun nyin jù eyiti a ti wasu fun nyin lọ, jẹ ki o di ẹni ifibu" (Galatia 1:8). O mọ̀ pé awọn oniwaasu yoo wá ti yoo wi pe ki i ṣe ọ̀ràn-an-yàn pe ki a di atunbi. Awọn miiran yoo wi pe o ṣe e ṣe fun eniyan lati ri igbala ati isọdimimọ́ papọ̀ lẹẹkan naa. Awọn miiran yoo wi pe ki i ṣe dandangbọ̀n fun eniyan lati lọ ṣe atunṣe fun awọn ti o ti hu iwa ti kò tọ́ si. Gbogbo nnkan wọnyii, ati ju bẹẹ lọ, jẹ ẹ̀kọ́ èké. Ẹni ti o ba n waasu nnkan wọnyii di ẹni ifibu.

**Awọn ti a fi Ẹjẹ Rẹ̀ Rà**

Ijọ yii ṣọwọn fun Paulu. O ti ṣetan lati fi ẹmi rẹ lelẹ ki awọn eniyan wọnyii ba le ri igbala. Ṣugbọn ijọ tilẹ tun ṣọwọn ju eyi lọ fun Oluwa nitori pe Ẹjẹ Rẹ̀ ni O ti fi rà a. Kò sí ohun miiran laye ti o le san gbese ẹ̀ṣẹ wa. Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati sanwo irapada wa, nitori naa a ṣọwọn fun Un gidigidi.

**Irinṣẹ Eṣu**

Ki i ṣe kikì pe awọn oniwaasu èké yoo wá sinu agbo lati mú wọn gba ọna ti o rọrun nikan, ṣugbọn awọn miiran laaarin wọn yoo sẹ́ igbagbọ́. Wọn yoo di agberaga, wọn a si fẹ ki awọn eniyan fẹran wọn ki wọn si maa bú ọlá fun wọn dipo Jesu ati awọn iranṣẹ Rẹ̀ tootọ. Wọn a maa fi ète wọn pọ́n awọn eniyan, wọn a si maa fi abẹtẹlẹ wá ojurere wọn, wọn a si fà wọ́n sẹyin kuro ninu ijọ sinu ẹ̀kọ́ titun.

Ki i ṣe aarin ijọ Efesu nikan ni eyi gbé ṣẹlẹ. Ọ̀kan ninu awọn ohun ija Satani ti o n fi ba awọn Onigbagbọ́ jà ni igberaga. A maa tọ ẹni ti n rìn nipa ti ẹmi wá, a si maa sọ si i leti kẹlẹkẹlẹ pe eniyan pataki ni i ṣe ati pe o kún fun iṣẹ rere pupọ. O si le wi pẹlu pe awọn eniyan kò mọ riri iṣẹ rẹ̀ ati pe o yẹ ki o fa oju awọn ti yoo mọ rírì iṣẹ rẹ̀ mọra.

Awọn ẹlomiran a maa wi pe, "Kuro lẹhin mi, Satani, --- nitori iwọ ko rò ohun ti iṣe ti Ọlọrun, bikoṣe eyiti iṣe ti enia." Igbagbọ́ awọn eniyan bẹẹ a maa fidimulẹ̀ ninu Ọlọrun ati awọn alakoso ti O fi sibẹ. Ṣugbọn awọn ẹlomiran yoo feti si i, lai pẹ wọn a bẹ̀rẹ si i rò pé awọn eniyan kò kà wọn si mọ́. Bi wọn kò ba le pa gbogbo ijọ lọkàn dà si ọna ti wọn, wọn yoo fa awọn eniyan diẹ bọ̀di, wọn yoo si dá ijọ ti wọn silẹ. Bayii ni ọ̀pọlọpọ ẹsin èké ti ṣe bẹrẹ.

Jesu wi pe bi a ba gbé Oun soke, Oun yoo fa gbogbo eniyan sọdọ ara Rẹ̀. Iwaasu Paulu nigba gbogbo duro lori Jesu, bẹẹ ni kò si fẹ gbé ara rẹ̀ ga. O sọ pe oun ti sin Oluwa pẹlu "irẹlẹ ọkàn gbogbo, ati omije pipọ, pẹlu idanwò."

Nigba kan awọn eniyan ni akanṣe ifẹ si Paulu. Awọn ẹlomiran si yan iranṣẹ Ọlọrun kan ti a n pe ni Apollo fẹ́. Paulu beerè: "Kini Apollo ha jẹ? kini Paulu si jẹ? bikoṣe awọn iranṣẹ nipasẹ ẹniti ẹnyin ti gbagbọ́" ninu Jesu (1 Kọrinti 3:5). O beerè pe: "Iṣe Paulu li a kàn mọ agbelebu fun nyin bi? tabi li orukọ Paulu li a baptisi nyin si?" (1 Kọrinti 1:13). Iṣẹ ti wa ni lati waasu Jesu, ki i si i ṣe eniyan. Ni tootọ a maa n bu ọlá ati ọ̀wọ fun awọn ti wọn sọ fun wa nipa Jesu; ṣugbọn ẹ jẹ́ ki a ranti pe Jesu ni Apata ti a kọle igbagbọ́ wa le lori. Bi gbogbo eniyan tilẹ kùna, Oun yoo duro laelae.

**Ninu Iṣọkan Ẹmi**

Fun ọdun mẹta ni Paulu fi n kilọ fun awọn eniyan wọnyii nipa ewu ti ó wà ni ọjọ iwaju. Akoko tó lati fi wọ́n silẹ, o si gbadura pe ki Ọlọrun pa wọn mọ́ ninu oore-ọfẹ Rẹ̀.

Iṣoro wà niwaju fun Paulu. O wi pe: "Ọkàn mi nfà si ati lọ si Jerusalẹmu, laimọ̀ ohun ti yio bá mi nibẹ: bikoṣe bi Ẹmi Mimọ́ ti nsọ ni ilu gbogbo pe, ide on iya mbẹ fun mi." Awa ha le fi igboya tẹ̀ siwaju bi Paulu ti ṣe bi a ba mọ̀ pe wahala wà fun wa niwaju? Bi a ba mọ̀ pe ninu ilu kọọkan ti a ba wọ̀, ẹni kan wà nibẹ ti o n fẹ lati ṣe wa ni ibi? A ha le tẹ̀ siwaju sibẹ lati maa tan Ihinrere kalẹ?

Ihinrere ha ṣe pataki fun wa to bẹẹ ti a le fi ẹmi wa lelẹ fun un? Ọkẹ aimoye eniyan ni o ti ṣe bẹẹ bi ọdún ti n gori ọdún. Wọn kò ka ẹmi wọn si titi de oju ikú, wọn si le wi pẹlu Paulu pe: "Lati isisiyi lọ a fi ade ododo lelẹ fun mi, ti Oluwa, onidajọ ododo, yio fifun mi li ọjọ na, ki si iṣe kiki emi nikan, ṣugbọn pẹlu fun gbogbo awọn ti o ti fẹ ifarahàn rẹ̀" (2 Timoteu 4:8).

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni Paulu sọ nipa igbagbọ́ rẹ̀ nigba ti ọjọ ayé rẹ̀ n lọ si opin?

2 Bawo ni "ipinnu Ọlọrun" ti Paulu waasu rẹ̀ ti pọ̀ tó?

3 Ki ni ṣẹlẹ si ọdọmọkunrin ti o ṣubu lulẹ lati ojú ferese nigba ti Paulu waasu titi di ọganjọ oru?

4 Ki ni Paulu sọ nipa ihinrere miiran ti o yatọ si eyi ti o ti waasu?

5 Eeṣe ti ijọ fi ṣọwọn fun Jesu?

6 Tani Paulu ni lọkan nigba ti o n sọ nipa awọn ikookò?

7 Darukọ ọ̀kan ninu awọn irinṣẹ Satani?

8 Ọna wo ni Satani n gbà dán Onigbagbọ́ wò?

9 Bawo ni Ihinrere ti ṣe pataki tó fun Paulu?